# Ìlo Ọfọ̀ Nínú Àṣàyàn Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá

*Kareem, Múdàṣírù Àbáyọ̀mí PhD & Adu, Olúbùnmi Tèmítọ́pẹ́ PhD*


## Àṣamọ̀

*Isẹ́ yìí ṣe àgbéyẹ́wò ìlò ọfọ̀ nínú àṣàyàn fíìmù àgbéléwò Yorùbá. Yorùbá lóni ọfọ̀, ọfọ̀ lóni Yorùbá. Nípa báyìí bí ìkarahun ọfọ̀ bá fà, ìgbín Yorùbá a sì tẹ̀le e. Işé yìí fi ìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé ipa tí ọfọ̀ ń kó lórí oògùn kò kéré. Iṣẹ́ yìí tún jẹ́ kí á mọ̀ pé ọfọ̀ ni kọ́kọ́rọ́ tí a fi ń sílẹ̀kùn oògùn. Àwọn fíìmù àgbéléwò tí a ṣe àmúlò wọn nínú iṣẹ́ yìí jẹ́ mẹ́jọ. Àwọn náà ni,* Ọ̀pá Àṣẹ, Ẹní Jogún, Ògún Lákáayé, Ònà Lójìn, Basọ̀run Gáà, Oníkòyí, Orí Ẹni àti Ògbórí Ẹlẹ́mọ̀shọ́. *A ṣe àmúlò àwọn fíìmù àgbéléwò wọ̀nyí nítorí pé àwọn aṣefíìmù ṣe àgbékalẹ̀ ìlò ọfọ̀ nínú fíìmù àgbéléwò wọ̀nyí. Àkójọpọ̀ èdè fún àyẹ̀wò iṣẹ́ yìí ni a gbà láti orísun méjì, orísun àkọ́kọ́ níí ṣe pẹ̀lú fíìmù àgbéléwò àti ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò. A ṣe àkójọ àti àdàkọ fíìmù àwọn òṣèré tí a yàn láàyò. Àwọn òṣèré náà ni Adébáyọ̀ Fálétí, Lérè pàímọ́, Yínká Quadri àti Táíwò Hassan. A ṣe àsàyàn àwọn òṣèrè wọ̀nyí nítorí pé wọn jẹ́ gbajúgbajà àti ìlú-mọ̀-ọ́n-ká nídìí iṣẹ́ fíìmù ṣíṣe. Ìjìnlẹ̀ ìfọ̀rọ̀-wáni-lẹ́nu-wò wáyé pẹ̀lú àwọn òṣèré wọ̀nyí láti lè ṣe àfàyọ ẹ̀rí lórí ìlò lítíréṣọ̀ alohùn tí ọfọ̀ jẹ́ ọ̀kan lára lítíréṣọ̀ alohùn wọ̀nyí. Àbájáde iṣẹ́ yìí fihàn pé ìlò ọfò nínú fíìmù àgbéléwò Yorùbá ní ipa pàtàkì tí ń kó pàápàá jùlo nipa ìṣelójò àwọn ọfọ̀ Yorùbá fún àwọn ìran tó ń bọ̀ àti fífi agbára ọ̀rọ̀ hàn. Nínú àdàkọ wa ni a ti ṣe àfàyọ àwọn ọfọ̀ tí a ṣe àmúlò wọn nínú iṣẹ́ yìí. Orísun kejì ni a ṣe àtòjọ rẹ̀ láti inú ìwé jọ́nà àtìgbàdégbà àti ẹ̀rọ ayélujára, pàápàá jùlọ èyí tó níí ṣe pẹ̀lú àkòrí iṣẹ́ yìí. Iṣẹ́ yìí ṣe àfikún fún òye áti ìmọ̀ wa pé àjọṣepọ̀ tó gbópọn wa láàrin àwùjọ, ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ àti aṣefíìmù. Bákan náà iṣẹ́ yìí tún jẹ́ kí á mọ̀ pé fíìmù jẹ́ ìsínjẹ àwùjọ tí àwọn aṣefíìmù máa ń mú wá sí ìrántí àwọn ololùfẹ́ wọn gẹ́gẹ́ bí díńgí àwùjọ.*


*Kókó Ọ̀rọ̀:* *àyájọ́, fíìmù, oògùn, ọfọ̀*

## Ìfáárà

Oògùn tí kò ṣe é fojúrí tí Yorùbá máa ń lò fún ìrànlọ́wọ́ ni àyájọ́. Oògùn yìí jẹ́ gbólóhùn èdè Yorùbá tí a lè kọ gẹ́gẹ́ bí orin tàbí sọ ní èdè ṣákálá. A sì tún lè ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ ní ìlànà ewì. Òhun ni Yorùbá ń lò láti ṣe ohun pàtàkì tí wọ́n ń fẹ́ kí ó lè rí bí wọ́n ti fẹ́. Àmúsẹ rẹ̀ a máa jẹ́ àrà ọ̀tọ̀ tí ó sì jọni lójú. Òhun ni gbólóhùn Yorùbá tí a lò láti lè mú kí èrò ọkàn kan jáde, kí ìyípadà le dé bá ẹni tàbí ohun tí ó ń gbọ́ wa (tí a ń sọ̀rọ̀ sí). Irúfẹ́ ìyípadà yìí lè jẹ́ rere tàbí ibi. Èyí wà lọ́wọ́ irúfẹ́ èsì tí apọfọ̀ ń retí lẹ́yìn ọfọ̀ pípè rẹ̀.

Nígbà mìíràn láti bẹ̀ ẹ́ tàbí kí èrò ọ̀kan rẹ̀ yípada sí èyí tí ó ti ní tẹ́lẹ̀. Òhun náà ni a fi ń sọ ìtàn nipa àwọn irúnmọlẹ̀ (ẹ̀mí àìrí bí òòṣà) alájọbí, àwọn akọni ayé-àtijọ́ àti àwọn alágbára tí ń bẹ nínú afẹ́fẹ́ láti lè bẹ̀bẹ̀ ohun kan lọ́wọ́ wọn tàbí láti lè lo agbára wọn fún àmúsẹ ohun kan.

Ìwọ̀nyí fíyé wa pé a lè pín oògùn àyájọ́ sí àwọn ìsọ̀rí díẹ́. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé nínú ìsọ̀rí mìíràn ó lè di ohun àfojúrí. Síbẹ̀ oògùn àmúsẹ ohun kan tàbí òmíràn náà ló jẹ́. Àwọn ìsọ̀rí yìí ni ọfọ̀, ògèdè, gbètugbètu, ààsán, ìtàn ríró̩, àkáábá, ààbò, ààbà àti àgádágodo wà. Nínú àwọn ìsọ̀rí òkè wọ̀nyí, ohun tí ó jẹ́ iṣẹ́ yìí lógún ni ọfọ̀.

Nígbà tí Yorùbá bá ṣe oògùn kan pẹ̀lú ewé, egbò, èèpo igi, ẹ̀yà ẹranko tàbí ti ènìyàn pàápàá. Irúfẹ́ àwọn oògùn bẹ́ẹ̀ kì í jẹ́ àfi ìgbà tí wọ́n bá pe àwọn àkójọ wọ̀nyí ni orúkọ àbísọ wọn. Nipa báyìí, gbólóhùn tí Yorùbá máa ń lò nígbà tí wọ́n bá ṣe oògùn tán láti bá irúfẹ́ oògùn bẹ́ẹ̀ sọ̀rọ̀ ni ọfọ̀. Yorùbá máa ń rán àwọn àkójọ wọ̀nyí ní isẹ́. Irúfẹ́ iṣẹ́ bẹ́ẹ̀ le jẹ́ èyí tí ó lé tún nǹkan ṣe tàbí èyí tí ó lé ba nǹkan jẹ́.

Nígbà mìíràn, Yorùbá a máa jẹ ohun kan lẹ́nu bí ataare, epo pupa tàbí obì kí wọn tó lè pe ofọ̀. Wọ́n lé da omi ìdí ìgbín sílẹ̀ tàbí kí wọn da ẹmu tàbí ẹ̀jẹ̀ ẹran sílẹ̀ kí wọn tó máa pe ọfọ̀.

Nipa báyìí, a kò le dá àwọn aṣefíìmú lẹ́bi nipa ṣíṣẹ àmúlò ọfọ̀ nínú àgbékalẹ̀ fíìmù àgbéléwò wọn.

## Díẹ̀ Lára Iṣẹ́ Tó Wà Nílẹ̀ Lórí Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá

Ọ̀pọ̀ àwọn onímọ̀ ló ti ṣiṣẹ́ lórí fìímù àgbéléwò Yorùbá. Díẹ̀ lára wọn ni Adélékè (1995), Adágbádá (2005) àti Kareem (2015). Àkòrí iṣẹ́ àwọn onímọ̀ wọ̀nyí dá lórí àfojúsùn wọn nipa fíìmù àgbéléwò Yorùbá. Ohun tí ó jẹ́ àfojúsùn Adélékè (1995) ni ipa òǹwòran lórí fíìmù. Nínú iṣẹ́ yìí Adélékè wo ipa tí oníruurú àwọn ènìyàn tó ń wo fíìmù ní lórí bí àwọn òǹwòran ṣe tẹ́wọ́ gba fíìmù sí. Bákan náà iṣẹ́ yìí tún ṣé àgbéyẹ̀wò ìhà tí àwọn òǹwòran kọ sí ìtàn inú fíìmù, ibùdó ìtàn, ẹ̀dá ìtàn, òsèré àti èdè. Adágbádá (2005) ṣe àgbéyẹ̀wò oríṣìíríṣìí àwọn ẹ̀dá ajẹmábo nídìí iṣẹ́ fíìmù. Lẹ́yìn èyí ni ó ṣàlàyé ipa tí àwọn obìnrin ń kó nídìí iṣẹ́ fíìmù. Àfojúsùn iṣẹ́ Kareem (2015) ni àgbéyẹ̀wò ìjẹyọ lítírésọ̀ alohùn, àṣà àti ẹ̀sìn ìbílẹ̀ Yorùbá nínú àṣàyàn fíìmú àgbéléwò.

Àwọn ohùn àbáláyé mẹ́rin kan wà tó máa ń kọ́wọ̀ọ́rìn ní àwùjọ Yorùbá. Àwọn ni ọfọ̀, ògèdè, ààsán àti àti àyájọ́ (Ọdẹ́jọbí 1991:92). Ọfọ̀ àti ògèdè súnmọ́ ara wọn tó bẹ́ẹ̀ tó fi ṣòro láti tọ́ka sí ìyàtọ̀ wọn. Fọ́lọ́runsọ́ (1982:13) tile gbà pé ọfọ̀ náà ni Yorùbá ń pè ní ògèdè.

Olọ́gundúdú (2008:42) sọ̀rọ̀ nípa ọfọ̀ ó ní "Yorùbá believe that incantation and the spoken words are more powerful than charms (Yorùbá gbàgbọ́ pé ọfọ̀ àti ọ̀rọ̀ ẹnu ní agbára ju oògùn lọ).

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (2011:15) sọ̀rọ̀ nipa àṣẹ àti ọfọ̀, ó ni:

> Adélutí ni orúkọ ti àṣẹ ń jẹ́. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé gbogbo nǹkan ló létí tó fi lè gbọ́ ọ̀rọ̀. Tí apọfọ̀/apàyájọ́ bá ti lè mọ orúkọ àṣírí ẹni tí ó ń pa àṣẹ fún, kía ni yóò tatí were.

Ohun tí Ọ̀pẹ́fèyítìmí ń sọ ni pé orúkọ àṣírí ṣe pàtàkì kí á tó lè pàṣẹ fún ènìyàn. Ṣùgbọ́n kì í ṣe gbogbo ìgbà ni àwọn Yorùbá máa ń nílò orúkọ àṣírí ẹni tí wọ́n fẹ́ pàṣẹ fún kí wọ́n tó pa a. Inú ẹsẹ ifá ni àyájọ́ ti wá Ọlátúnjí (1981:3) jẹ́rìí sí èyí pé àyájọ́ ju ẹsẹ ifá lọ, èyí tó jẹ pé ọ̀fọ̀ inú rẹ̀ ló ṣe pàtàkì jù. Ọlátimtán (1980:15) gbà pé ìtàn Ifá ni àyájọ́, ọ̀fọ̀ a sì máa wà nínú rẹ̀. Rájí (1991:x) tilẹ̀ sọ pé wọn a máa pe ògèdè tàbí àásán lu ẹni tí kò ṣeni ṣùgbọ́n tí a kórira.

Fábùnmi (1977: vii) sọ pé "àyájọ́ ohun Ifẹ̀ jẹ́ ìpèdè tàbí ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ ẹnu tí àwọn ará àtijọ́ máa ń lò láti ṣe ọ̀pọ̀lọpọ̀ nǹkan nílé ayé. Ohun tí Fábùnmi ń sọ ni pé kí a tó lè pe nǹkan kan ní àyájọ́ irúfẹ́ nǹkan bẹ́ẹ̀ gbọ́dọ̀ jẹ́ ògèdè tàbí ìjìnlẹ̀ ọ̀rọ̀ ẹnu àwọn ará àtijọ́ ṣùgbọ́n Fábùnmi kò pàálà láàrin àyájọ́ àti ọ̀fọ̀.

Ọ̀pẹ́fèyítìmí (1984: 48) sọ pé:

> Ìwádìí mi fi hàn wí pé púpọ̀ nínú àwọn àyájọ́ ló ni gbólóhùn "díá fún" lóòótọ́ ṣùgbọ́n kì í ṣe gbogbo ọ̀fọ̀ tí kò bá ní gbólóhùn yìí ni kì í ṣe àyájọ́.

Tí a bá wo àríwísí àwọn onímọ̀ òké wọ̀nyí nipa ọ̀fọ̀ àti àyájọ́, ìyàtọ̀ kan gbòógì tí a lè rí tọ́ka sí ni pé a lè tọpasẹ̀ orísun àyájọ́ lọ sínú ẹsẹ Ifá, ṣùgbọ́n a kò le tọpasẹ̀ ọ̀fọ̀ lọ sínú Ifá. Ọ̀fọ̀ ni a lè pé ní oríkì àdámọ́ àwọn èròjà tí a fi ṣe oògùn.

Àwọn Yorùbá máa ń lo ọ̀fọ̀ fún iṣẹ́ pàtàkì kan yálà fún ire tàbí fún ibi. Wọ́n a má a lò ó lásìkò ìṣòro. Ìgbàgbọ́ àwọn Yorùbá ni pé bí a bá pe ọ̀fọ̀ bí a ti ń pè é, ó di dandan kó jẹ́. Nínú àwọn fíìmù àgbéléwò Yorùbá, a rí ìlò àwọn gbólóhùn àṣẹ wọ̀nyí.

Nínú fìmù àgbéléwò *Ọ̀pá Àṣẹ* láti ọwọ́ Táíwò Hassan, a rí àwọn omidan tí wọ́n lọ pọnmi lódò Àìfọ̀ wá fún Ìyálóde. Àwọn omidan náà pọn omi tí a wí yìí wá sí ibi ibùdó ìtọ́jú àwọn aláìsàn tí Ìyálóde ń tọ́jú. Bí wọn ti sọ ìkòkò orí wọn kale ni Ìyálóde ki ọ̀pá àṣẹ ọwọ́ rẹ̀ bọ ọ̀kan nínú ìkòkò omi tí wọ́n pọn wá fún un. Lẹ́yìn tí ó júbà lọ́wọ́ àwọn tó layé àti àwọn Ìyálóde tí ó ti jẹ síwájú rẹ̀ tán, ó ki ọ̀fọ̀ bọnu ó ní:

*Torí pé kín ni?*
*Tútùtútù báyìí làá rọdẹ*
*Tútù làá rọ bàbà*
*Tútù làá rọ bàbà*
*Tútù làá rọ bàbà*
*Tútù làá ròjé*
*Àtòjo àtẹ̀ẹ̀rùn ilé olúwẹri kì í gbóná* (*Ọ̀pá Àṣẹ*)

Ọ̀fọ̀ ẹ̀rọ̀ ni irúfẹ́ ọ̀fọ̀ òkè yìí. Àwọn Yorùbá a máa lò ó láti tu àwọn ènìyàn tí wọ́n bá wà nínú ìnira lára. Bí àwọn Yorùbá ti máa ń lò ó náà ni Ìyálóde ṣe lò ó. Ẹnu

Ìyálóde tí ó yẹ kí á ti gbọ́ ọ náà ni a ti gbọ́ irúfẹ́ ọfọ̀ yìí. Ìyálóde ló ni ẹ̀tọ́ láti lo ọ̀pá àṣẹ fún ìmúlárada àwọn aláìsàn. Ìyálóde mú ọ̀pá àṣẹ rẹ̀ nígbà tí ó pe ọfọ̀ yìí tán ó sì fi kan orí àwọn aláìsàn náà ní ọ̀kọ̀ọ̀kan. Ara sì bẹ̀rẹ̀ sí í tu àwọn aláìsàn náà pẹ̀sẹ̀. Lẹ́yìn tí àwọn aláìsàn gba ìdáǹdè tán ni wọ́n bẹ̀rẹ̀ sí dìde ní ọ̀kọ̀ọ̀kan. Gẹ́gẹ́ bí àkóónú ọfọ̀ Ìyálóde, ara tu àwọn tó wá fún ìtọ́jú. Ọfọ̀ náà sì jẹ́ iṣẹ́ tí Ìyálóde rán an.

Nígbà tí ìlú rójú, tí ìlú kò rí ààyé, ara ni gbogbo ará ìlú Igbó-Ewé nítorí àwọn ọ̀bàyéjẹ́ ẹ̀dá. Ọba àti àwọn ìjòyè ráńṣẹ́ sí pàjẹ́polóògùn láti wá bá wọn fọ ilú mọ́ nipa mímú àti fífojú àwọn ọ̀bàyéjẹ́ náà hàn. Pàjẹ́polóògùn wá lóòótọ́, ó sì ṣe iṣẹ́ rẹ̀ bí iṣẹ́. Ọjọ́ kan ni ti olè, ọjọ́ gbogbo ni ti olóhun. Ọjọ́ tí Gìrìpá àti àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀ fẹ́ fi ìlú sílẹ̀ ni wọ́n ṣe alábàápàdé Pàjẹ́polóógún. Bí irin bá kan irin dandan ni kí ọ̀kan tẹ̀ fún èkejì. Àwọn méjèèjì dán agbára wọn wò nípa ṣíṣe àmúlo ọfọ̀. Ọ̀kan nínú ọfọ̀ tí Pàjẹ́polóógùn pè sí Gìrìpá lọ báyìí, ó ní:

> *Ẹnu mi àṣẹ*
>
> *Gbogbo ohun tí mo bá wí lónìí*
>
> *Ó dàṣẹ*
>
> *Àṣẹ tí ń bẹ lára ọká lọká fi i ṣoró*
>
> *Èyí tí ń bẹ lẹ́nu ìjímèrè ló fi ń gbìjàjà.* (*Ọ̀pá Àṣe*)

Ọfọ̀ àṣe ni ọfọ̀ òkè yìí. Àwọn Yorùbá a máa lò ó láti fi agbára àṣẹ mú ọ̀tá wọn. Bí àwọn Yorùbá ti máa ń lò ó náà ni Pàjẹ́polóògùn ti lò ó láti fi kápá Gìrìpá. Pàjẹ́polóògùn tó yẹ kí ó lò náà ni ó lò ó nítorí ipò agbára tí onífíìmù gbé lé e lọ́wọ́. Lẹ́yìn tí ó pe ọfọ̀ yìí tán, ó na ọ̀pá ọwọ́ rẹ̀ sí Gìrìpá, ó sí pàṣẹ fún àwọn ọmọ ẹ̀yìn Gìrìpá, ó ní:

> *Kí iyè tiyín ó ra*
>
> *Amúnimúyè kó múyè yín lọ* (*Ọ̀pá Àṣẹ*)

Gẹ́gẹ́ bí ìgbàgbọ́ tí àwọn Yorùbá ní nínú ọfọ̀, Pàjẹ́polóògùn náà ṣe àfihàn ìgbàgbọ́ yìí nínú fíìmù "Ọ̀pá Àṣẹ" Bí Pàpèpolóògùn ti pe ọfọ̀ yìí tàn tí ó na ọ̀pá ọwọ́ rẹ̀ sí Gìrìpá, ó di ọ̀dẹ̀ tí ó sì ń wò sùn ùn bí orí ẹran. Iyè tó wà nínú àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀ náà sì pòórá pẹ̀lú. A lè sọ wí pé ọfọ̀ yìí jẹ́ iṣẹ́ tí wọ́n rán an nítorí pé ọfọ̀ yìí ni Pàjẹ́polóògùn pè kí ó tó lè ri Gìrìpá àti àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀ mú. Lẹ́yìn èyí ni ó kó gbogbo àwọn ọ̀bàyèjẹ́ náà lọ́ sí iwájú ọba.

Nínú fíìmù àgbéléwò "Ẹ̀gbà Ọwọ́" láti ọwọ́ Yínká Quadri ni a tún ti rí ìjẹyọ ọfọ̀ mìíràn. Àìsàn wárápá ń yọ Tìmíléyìn ọ̀gá Zainab lẹ́nu. Nígbà tí Zainab rì èyí, ó gbìyànjú láti mú Tìmúlẹ́yìn lọ sí ọ̀dọ̀ bàbá rẹ̀ tí ó jẹ babaláwo. Ìyá Tìmílẹ́yìn sì tẹ̀lé wọn pẹ̀lú. Bàbá Zainab ṣàlàyé bú wọ́n ti máa ṣe ewé àti egbò tó jẹ mọ́ àìsàn Tìmílẹ́yìn. Nínú ọ̀rọ̀ bàbá Zainab, ó ní:

*Lẹ́yìn ìgbà tó bá wẹ̀ tan, kí ìwọ wá mú obì àbàtà, tí ń bẹ láàrin rẹ̀, kó o là á, kó o wá mú awẹ́ kan níbẹ̀, kó o fi sí i lẹ́nu. Ní kí ó pa ẹnu dé mọ́ ọn, tó bá pa ẹnu dé mọ́ ọn nígbà tó bá ń jẹ ẹ́ lọ́wọ́, ìwọ ó máa wí báyìí pé:*

*"Àgùnmọ̀nà kan kì í gungi dórí..."*

*"Àgùnmọ̀nà kan kì í gungi dórí..."*

*"Àgùnmọ̀nà kan kì í gungi dórí..."*

(*Ẹni Jogun*)

Ọfọ̀ ètùtù ni orúfẹ́ ọfọ̀ òkè yìí. Àwọn Yorùbá a máa lò ó láti ṣe ètùtùj àìsàn kan lẹ́yìn ìgbà tí wọ́n bá ṣe àkójọpọ̀ èròjà oògùn tàn. A lè sọ pé bí wọ́n ti ń lò ó nílẹ̀ẹ̀ Yorùbá náà ni wọ́n ti lò ó nínú fíìmù àgbéléwò "Ẹ̀gbà Ọwọ́." Baba Zainab (babaláwo) tó yẹ kí ó pè é náà ni ó pè é. Oògùn tí bàbá Zainab ṣe fún Tìmílẹ́yìn ni ó yọ ọ́ kúrò nínú àìsàn wárápá. A kó gbọdọ̀ gbàgbé pe àgùnmọ̀nà àti obì àbàtà wà nínú èròjà oògùn tí wọ́n ṣe fún Tìmílẹ́yìn, wọ̀n sì gbọ́dọ̀ pé oríkì èròjà náà kí oògùn yìí tó lè ṣiṣẹ́. Bí àwọn Yorùbá náà ti máa ń lo ọfọ̀ náà ni wọ́n ti ṣe àmúlò rẹ̀ nínú fíìmù yìí.

Nínú fíìmù "Ẹni Jogún," ọ̀rẹ́ ìyá Ọlákúnlé mú ìyá Ọlákúnlé lọ sí ilé babaláwo lórí ọ̀rọ̀ ọmọ rẹ̀, Ọlákúnlé. Àwọn obìnrin a máa lo agbára láti dáàbo bo ìgbéyàwo wọn nílé ọkọ wọn. Babaláwo yìí ni ó ṣe oògùn àfọ̀ṣẹ fún ìyá Ọlákúnlé láti lè máa mú ìfẹ́ ọkàn rẹ̀ ṣẹ. Oògùn àfọ̀ṣẹ yìí ni ìyá Ọlákúnlé fi ṣe gbogbo aburú tó ṣe nínú fíìmù àgbéléwò "Ẹ̀ní Jogún." Nígbà tí babaláwo parí iṣẹ́ náà tí ó gbé e lé ìyá Ọlákúnlé lọ́wọ́, ó kọ́ ọ bí yóò ṣe máa pe ọfọ̀ sí oògùn àfọ̀ṣẹ náà. Ọfọ̀ náà lọ báyìí:

*Àfọ̀ṣẹ*
*Àfọ̀ṣẹ ni tifá*
*Àwíṣẹ ni tọ̀pẹ̀lẹ̀*
*kọ̀ǹkọ̀ kì í kọhùn odò*
*káyé má kọhùn mi* (*Ẹni Jogún*)

Ọfọ̀ àṣẹ ni ọfọ òkè yìí. Àwọn Yorùbá a máa lò ó láti mú ìfẹ́ inú wọn ṣẹ lórí nǹkan kan tàbí òmíràn. Bí àwọn Yorùbá ṣe máa ń lò ó náà ni wọ́n ṣe lò ó. Babaáwo tó yẹ kí ó pe ọfọ̀ yìí náà ni ó pè é nípasẹ̀ oògùn tó ṣe fún ìyá Ọlákúnlé. Ọ̀kan nínú iṣẹ́ ibi tí ìyá Ọlákúnlé fi ọfọ̀ àfọ̀ṣẹ yìí ṣe ni pé ó fi yí àkọsílẹ̀ ìlànà ogún pínpín ti Ọlátúndé Àrẹ̀mú (ọkọ rẹ̀) ti ṣe padà sí orúkọ ọmọ rẹ̀ Ọlákúnlé Àdìṣá. Ọfọ̀ yìí náà ni ó lò láti fi pa ọkọ rẹ̀ nígbà tí ó ń bọ̀ láti ọ́ọ́fíìsì lọ̀yà. Nígbà tí ó fẹ́ lo àfọ̀ṣẹ yìí fún ọkọ̀ rẹ̀, ó ni:

*Ha! Ha!! Ha!!!*
*Àwíṣẹ ni tifá*

*Àfọ̀sẹ ni tọ̀pẹ̀lẹ̀*
*kọ̀ǹkọ̀ kì í kọhùn odò.*
*Kí ìwọ Lákúnlé Àrẹ̀mú*
*Ó má kọhùn èmi Ọmọ́wùmí o.*
*Ọlátúndé Àrẹ̀mú*
*Bí o ti ń lọ sí ọ́ọ́fíísì lọ́yà yẹn*
*Bí ó bá ti ń débẹ̀*
*Mo fẹ́ kí gbogbo wîlì yẹn.*
*Yípadà sí orúkọ Ọlákúnlé Àdìṣá*
*Ọmọ èmi Ọmọ́wùnmí*
*Bí ó bá ti wà ń parí gbogbo wîlì yẹn tán*
*Mọ́tò tó gbé ẹ lọ ọ̀hún*
*Náà ni kó lọ sẹkú pa ẹ́ o.*
*Mo fẹ́ kí o lọ wa ara rẹ̀ pa*
*Bẹ́ẹ̀ni* (*Ẹní Jogún*)

Gbogbo èrò ọkàn ọmọ́wùmi ni ó wà sí ìmúṣẹ nípasẹ̀ oògùn àfọ̀sẹ yìí. Àkọ́kọ́ wọ́n yí orúkọ inú wíìlì padà sí orúkọ ọmọ Ọmọ́wùmí. Ẹ̀kejì, mọ́tò tí ọkọ rẹ̀ gbé lọ sí ilé lọ́yà náà ni ó ṣe ikú pa á nígbà tí ó ń bọ̀. Bí ọfọ̀ rere ti wà ní ilẹ̀ Yorùbá ni ọfọ̀ ibi náà wà pẹ̀lú. “Ibi” jẹ́ ìdàkekì “ire.” Ibi ni nǹkan òdì tí ẹ̀dá kò fẹ́ nígbà ti ire jẹ́ nǹkan ayọ̀ ti tẹrútọmọ máa ń gbàdúrà fún.

Nínú fíìmù “Ògún Lákáayé,” Ṣàngó gba ìyàwó Ògún. Èyí ni ó dá yánpọn-yánrin sílẹ̀ láàrin àwọn ọ̀rẹ́ méjì. Àwọn méjéèjì sì ń lérí sí ara wọn. Ní ọjọ́ kan tí inú bí Ògún lórí ọ̀rọ̀ ìyàwó rẹ̀ tí ṣàngó gbà, ó pé ọfọ̀ láti pe ẹ̀fúùfù jáde; ó ní:

*Ha!!! Ìjà ń bọ̀*
*Ìjà ti dé*
*Ṣàngó o*
*Olúkòso, Olùfínrìn,*
*O ti tọ́ mi o.*
*Afẹ́fẹ́lẹ́lẹ́ ní ṣewé oko wélewéle*
*Ẹ̀fúùfùlẹ̀lẹ̀ ní ṣewé àgbọn gbàgogbàgo*
*Wá pewé okò dà ń mi*
*Ẹ̀fúùlẹ̀lẹ̀*
*Parí igi dà ń mi*
*O payiayamaya*

*O pòyímàyinmàyin*

*Ẹ̀fúùfùlẹ̀lẹ̀ jẹ̀wọ́ agbára rẹ̀*

*Èmi Ògún dé Lákááyé Òṣìnmọlẹ̀* (*Ògún Lákáayé*)

Bí ògún ti pe ọfọ̀ yìí tán ni ẹ̀fúùfù líle dìde. Àwọn alágbára a máa ṣe àmúlò ọfọ̀ láti pàṣẹ fún nǹkan tí wọ́n bá fẹ́ rán níṣẹ́ bí ó ti jẹ yọ nínú fíìmù àgbéléwò "Ògún Lákáayé."

Nínú fíìmù àgbéléwò "Ọ̀nà Lójìn," inú Ọba Ọlórundá kò dùn lórí ọ̀rọ̀ Bọ̀sípò tó sọnù. Ọba Ìlúdùn rán àwọn bọ́baṣẹ̀lú sí Ọba Ọlọ́rundá láti bá ọba náà kẹ́dùn. Nígbà tí àwọn ìjòyè dé ọ̀dọ̀ ọba, ọba fi ẹ̀hónú rẹ̀ hàn sí àwọn ìjòyè Ìlúdùn. Ò gba àwọn ìjòyè ní ìyànjú láti ṣe àwàrí ọmọ náà ki oòrùn tó wọ̀ àti wí pé kí wọ́n máa retí ogun tí wọn kò bá rí Bọ̀sípò. Ọba pe ọfọ̀ láti pe iná jáde láti ẹnu. Iná yìí gbà mọ́ àwọn olóyè lára, wọ́n sì fi ẹsẹ̀ fẹ́ẹ. Ọfọ̀ náà lọ báyìí pe:

*Ọ̀tẹ́rẹ́rẹ́ ilẹ̀ ń yọ̀*

*Ojú kan ṣoṣo ni ògìrìsàkọ́ jókòó sí*

*Tí fìi rán igba ọkọ́ sóde ọ̀run* (*Ọ̀nà Lójìn*)

Ọfọ̀ àṣẹ ni ọfọ̀ òkè yìí. Àwọn Yorùbá a máa lò ó láti lè mú ifẹ́ inú wọn ṣẹ. Bí wọ́n ṣe ń lò ó ní ilẹ̀ Yorùbá náà ni ọba Ọlọ́rundá ṣe lò ó nínú fíìmù "Ọ̀nà Lójìn," Ọba Ọlọ́rundá tó yẹ kí ó lò ó náà ni o lò ó. Òun ló pe iná láti ẹnu tó si gbà mọ́ àwọn olóyè Ìlúdùn lára. Ọfọ̀ yìí jẹ́ iṣẹ́ tí ọba Ọlọ́rùndá ràn an. Àwọn Yorùbá náà a máa ṣe àmúlò ọfọ̀ bí Ọba Ọlọ́rundá ti ṣe àmúlò rẹ̀ nínú fíìmù yìí.

Nínú fíìmù àgbéléwò "Baṣọ̀run Gáà" babaláwo àti Gáà wà nílé agbára láti tún ró Gáà lágbára gẹ́gẹ́ bí ìṣe wọn. A rí ìròkò lóri iná pẹ̀lú odó mẹ́rin nílẹ̀ tí wọn tò ní méjìméjì sẹ́gbẹ̀ẹ́ ara wọn. Baṣọ̀run Gáà gbé ẹsẹ̀ méjì sínú odó. Ó bẹ̀rẹ̀, ó sì tún kó ọwọ́ méjì sínù odó mìíràn. Lẹ́yìn èyí ni Babaláwo da aṣọ pupa bo Gáà lórí, babaláwo ki ọfọ̀ bọnu, ó ní:

*Àgbá ń ró kugúkugú*

*Àrá ń ró gẹ̀gẹ̀gẹ̀gẹ̀gẹ̀*

*Mo ní ta ni ń dá gbẹ̀du ọ̀run*

*Wọ́n lọ́mọ eríwo ni*

*Mo ní kí ló ṣe tẹ́ ẹ fi ń dífá ńlá èyí fẹ́nìkan*

*Wọ́n ní tí wọ́n bá dáfá ńlá irú èyí fẹ́nìkan*

*Wọn a sì máa dìdàǹdá*

*Mo ní kíni ọmọ eríwo ń pè ní dàǹdá*

*Wọ́n ní, wọn a máa di gúnnugún, ẹyẹ inú igbó.*

*Wọ́n a dàkàlàmàgbò, ẹyẹ ẹ̀bá ọ̀dàn.*

*Wọ́n a dàkàlàmàgbò, ẹyẹ ẹ̀bá ọ̀dàn*
*Wọn a di tẹ́ǹtẹ́rẹ́ ẹyẹ ẹ̀gà ni ìmọ̀run*
*Wọn a dògòǹgò balẹ̀ ni tẹ̀rutẹ̀ru*
*Wọn a dògòǹgò bale ni tẹ̀rutẹ̀ru ọba nínú ẹ̀jẹ̀*
*Wọn a dògòǹgò bale ni tẹ̀rutẹ̀ru*
*Wọ́n a máa dẹfọ̀n, wọn a máa derin.*
*Ńjẹ́ Gáà ló fẹ́ dẹfọ̀n, kó sí derin lónìín o o o*
*Ẹ̀rù-gàlè kó dìde.*
*Wọn a dògòǹgò bale ni tẹ̀rutẹ̀ru*
*Wọn a máa dẹfọ̀n, wọn a máa derin.* (*Basọ̀run Gáà*)

Babaláwo Gáà rán ọfọ̀ yìí nísẹ́ láti lè jẹ́ kí Gáà parade di erin. Lóòótọ́ Gáà yíra padà ó sò derin nínú fíìmù yìí. Àwọn Yorùbá a máa lo ọfọ̀ láti lè mú èrò ọkàn wọn ṣẹ gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti ṣe àgbékalẹ̀ àti àmúlò rẹ̀ nínú fíìmú yìí. A lè pe ọfọ̀ yìí ni ọfọ̀ àṣẹ. Bí àwọn Yorùbá ṣe ń lò ó náà ni babaláwo Basọ̀run Gáà ṣe lò ó. Ẹni tí ó yẹ kí ó lò ó náà ni ó lò ó. Babaláwo Basọ̀run Gáà tó ṣe oògun agbára fún Gáà ló ṣe àmúlò ọfọ̀ yìí.

Ogun wọlé wẹ́rẹ́ tọ Basọ̀run Gáà. Àwọn ọmọ ogun Àrẹ-Ọ̀nà ń wá Gáà kiri. Gáà ti wọ́ lọ sí ilé agbára rẹ̀ bí ejò. Ilé agbára yìí ni ó ti ki ọfọ̀ bọnu, ó ní:

*Fírífìrí lojú rímú*
*Bọ̀ọ̀bọ làgùntàn ń wò*
*Bí òru, bí òru, kì í máà tán nísàlẹ̀ iyẹ̀wù*
*Ojú olóko ni tẹ̀ǹtẹ̀gìrì mọ̀ tíí gbẹ lẹ́yìn igi.* (*Basọ̀run Gáà*)

Ọfọ̀ òkè yìí ni Basọ̀run pè tí ó sí pòórá nínú ilé agbára. A rí i wí pé bí àwọn Yorùbá náà bá wà nínú ìṣòro kan tàbí òmíràn, wọn a máa ṣe àmúlò ọfọ̀ láti gba ara wọn sílẹ̀ bí Basọ̀run Gáà ti ṣe nínú fíìmù àgbéléwò yìí. Ọfọ̀ ìsújú ni àpẹẹrẹ ọfọ̀ òkè yìí. Àwọn Yorùbá a máa lò ó láti sọ ọ̀tá wọn sínú òkùnkùn. Bí àwọn Yorùbá ṣe máa ń lò ó náà ni Basọ̀run Gáà ṣe lò ó. Gáà pe ọfọ̀ yìí láti fi àwọn ọmọ ogun Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò sínú òkùnkùn láti má lè rí òun.

A rí ìjẹyọ ọfọ̀ mìíràn nígbà tí ogun gbóná girigiri. Nínú fíìmù àgbéléwò "Baṣọ̀run Gáà" Babaláwo Gáà náà ki ọfọ̀ bọnu láti lè rẹ́yìn Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò ó ní:

*Ha!!! Kakaǹfò*
*Ewúrẹ́ kì í gbénú ilẹ̀ kó rína*
*Àgùntàn kì í gbénú ilẹ̀ kó rína*

*Ọ̀sán, òru wọn kò gbọdọ̀ fojú kojú*
*Sóósó méjì, wọn kò gbọdọ̀ fojú kojú*
*Aìrẹ́ni tó jáwé adì sọ́nà*
*Èèwọ̀* (*Basọ̀run Gáà*)

Àwọn Yorùbá a máa ṣe àmúlò irúfẹ́ ọfọ̀ ìṣújú báyìí láti má lé jẹ́ ki ọ̀tá wọn rí wọn fún ìpalára. Ọ̀na tí àwọn Yorùbá máa ń gbà ṣe àmúlò ọfọ̀ yìí náà ni babaláwo Gáà ti ṣe àmúlò rẹ. Babaláwo Gáà ṣe àmúlò ọfọ̀ yìí láti dáàbò bo ara rẹ̀ lọ́wọ́ àwọn ọmọ ogun Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò. A rí i wí pé ọfọ̀ yìí kò ní ipa lórí Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò. Kí ojú máa ríbi gbogbo ara loògùn rẹ̀. Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò náà kí ọfọ̀ bọnu, ó ní:

*Àṣẹ iná niná fií jóko*
*Àṣẹ oòrùn loòrùn fií wọ̀*
*Èyí èwí ayé bá wí ni ẹ̀gbá ọ̀run ó gbà*
*Àṣubúlébú ni tegbèé*
*Ilẹ̀! Ilẹ̀!! Ilẹ̀!!!*
*Ìràwé kì í dọ́jọ́ ilẹ̀ kó súnnà*
*Ìràwé kì í dọ́jọ́ ilẹ̀ kó súnnà* (*Basọ̀run Gáà*)

Ọ̀fọ̀ òkè yìí ni Ààrẹ-Ọ̀nà Kakaǹfò pé tí ó sì fi kápá babaláwo Gáà. Bí ó ti pé ọfọ̀ yìí tán tí ó na ọpà ọwọ rẹ̀ sí babaláwo Gáà ni ó ṣubú tí ó sì kú. Ní ilẹ̀ Yorùbá àwọn alágbára méjì a máa ṣe àmúlò ọfọ̀ láti dán agbára wò gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ nínú fíìmù àgbéléwò yìí. Ọfọ̀ àṣẹ ni ọfọ̀ òkè yìí. Ọfọ̀ àṣẹ yìí ni àwọn Yorùbá máa ń lò láti fi pàṣe agbára lé àwọn ọ̀tá wọn lórí.

Nínú fíìmù "Oníkòyí," Akíntúndé ọmọ Oníkòyí fẹ́ láti lọ bá bàbá rẹ̀ lójú ogun. Ó wá sí ilé agbára láti gba agbára kún agbára nìtorí ìrìnàjò tó fẹ́ rìn. Ó kẹnu bọ ọfọ̀, ó ní:

*Mò ń jáde lọ báyìí*
*Àbọ̀ mi jẹ́ ó sunwọ̀n*
*Olùgbà, ọ̀gbàgbà, a gba ohun lọ́wọ́ olóhun*
*Oorun níí gba tọwọ ọmọdé*
*Oorun níí gba tọwọ àgbà*
*Tọmọdé bá sùn tọwọ rẹ̀ á bọ́*
*Tágbà bá sùn tọwọ rẹ̀ á bọ́*
*Kánkán lewé iná jó ni*
*Wàràwàrà lọmọdé toko èsí bọ̀*

*Ìwọ tí ó tọká mọ́lẹ̀ o ó ríjà ọká*

*Ìwọ tí ó tẹ àkeekè mọ́lẹ̀ o ó ríjà àkeekè*

*Èmi Akíntúndé dé*

*Ọmọ Oníkòyí o.* (*Oníkòyí*)

Bí Akíntúndé ti pe ọfọ̀ tán ni ó gba ojú ogun lọ. Ọ̀kàn nínú àwọn ọ̀tá Oníkòyí padà wọ ilé agbára Oníkòyí, o sì tọ̀ sí orí àwọn òrìṣà tí Oníkòyí kó sí inú ilé agbára rẹ̀. Èyí ni ó fà á ti àwọn òrìṣà wọ̀nyí fi bínú ti wọ́n sì padà lẹ́yìn Akíntúndé ọmọ Oníkòyí.

A lè pe irúfẹ́ ọfọ̀ òkè yìí ní ọfọ̀ agbára. Bí àwọn alágbára ti máa ń gbagbára kún agbára nílé agbára tí wọ́n bá fẹ́ lọ soju ogun ni onífìímù ti se àgbákalẹ̀ rẹ̀ nínú fìímù yìí.

Nínú fíìmù àgbéléwò "Oníkòyí" bákan náà, a rí àgbékalẹ̀ ọfọ̀, níbi tí Àrọ̀nì àti Rọ́bọnmi ti wá láti dá sẹ̀ríà fún Oníkòyí àti ìyàwó rẹ̀. Àrọ̀nì àti Rọ́bọnmi sì kó àwọn ẹmẹ̀wà wọn lẹ́yìn pẹ̀lú nítorí pé awo ni gbáwo nígbọ̀wọ́. Nígbà tí ìjà àwọn alágbára wọ̀nyí bẹ̀rẹ̀. Ẹ̀gíì ìyàwó Oníkòyí kẹnu bọ ọfọ̀, ó ní:

*Hàà, ó yá*

*Ẹbọ ní pẹlẹ́bọ*

*Àsàsí ní palásàsí*

*Òkìtì ọ̀gán tó bá jìn, orí ara rẹ̀ ní jìn-ín lé.*

*Békòló bá kọbè, orí ara rẹ̀ ní kọ ọ́ lé.*

*Bígbìn ín bá su àyà ara rẹ̀ ni fii ko*

*Bíjàpá básu àyà ara rẹ̀ ni fíi ko*

*Ìrìnkurìn ni wèrè rìn wọjà*

*Ó yá ìgbẹ́* (*Oníkòyí*)

Bí Ẹ̀gíì ti pe ọfọ̀ yìí tán ni àwọn ọmọ ẹ̀yìn Àrọ̀nì àti Rọ́bọnmì wọgbó lọ, kí iyè wọ́n tó sọ padà. Lẹ́yìn èyí ni wọ́n padà sọ́dọ̀ Ẹ̀gíì. A lè pé irúfẹ́ ọfọ̀ yìí ni ọfọ̀ àṣẹ. Bí àwọn alágbára ti máa ń ṣe àmúlò ọfọ̀ nìgbà tí wọ́n bá ń fagagbága náà ni onífíìmù ti se àgbákalẹ̀ rẹ̀ nínú fìímù àgbéléwò yìí.

Ọ̀dọ̀fin Mérégbógun àti Akaka Òkúta nínú fíìmù àgbéléwò Oníkòyí kó àwọn ọmọ ogun wọn wá sí orí ilẹ̀ àwọn ará Ọ̀yọ́. Wọ́n sì ṣe ìpinnu wí pé gbígbà ni àwọn yóò gba ilẹ̀ tó wà lápá ọ̀tún àti èyí tó wà lápá òsì. Akaka Òkúta kẹnu bọ ọfọ̀, ó ní:

*Ẹ wo ilẹ̀ tó wà lápá òsì yìí, àwa laní.*

*Ohùn rere làkèré fií fàjò*

*Ẹdá ló ní kí wọn ó máa dá tiwa sí rere*

*Ọwọ́ tàwa titẹ ewé olójòǹgbòdú*

*Ẹ̀sọ̀, ẹ̀sọ̀ la ó máa gbalẹ̀ lọ́wọ́ wọn*

*Ẹ wo ilẹ̀ tó wà lápá ọ̀tún yìí*

*A á gbìyànjú a á ṣe bí ọkùnrin*

*A ó gbà á mó tiwa* (*Oníkòyí*)

A lè pe irúfẹ́ ọfọ̀ òkè yìí ni ọfọ̀ arọ́bi. Ohun ti ọfọ̀ òkè yìí ń sọ ni pé ibi kò ní jẹ́ tiwọn. Bí àwọn Yorùbá ti máa ń pe irúfẹ́ ọfọ̀ òkè yìí ni onífíìmu ti ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Àgbékalẹ̀ ọfọ̀ arọ́bi yìí bá ìṣàmúlò rẹ̀ nínú àṣà ìbílẹ̀ Yorùbá mu.

Àwọn Rọ́bọnmi àti Àrọ̀nì kó ọmọ ogun wọn wá ká Oníkòyí mọ́lé. Oníkòyí kò sí nílé ṣùgbọ́n wọ́n bá ìyàwó rẹ̀. Nígbà tí wọ́n dé iwájú ilé Oníkòyí, Rọ́bonmi kí ọfọ̀ bọnu, ó ní:

*Ikú ata báyìí wá ní pata*

*Ikú obì níí pobì*

*Ọ̀rọ̀ ọlọ́rọ̀ lobì kú lé lórí*

*Àsáréká ọ̀tá ni ó pọ̀tá*

*Àsáréká mi ni ó pàwọ àti ọkọ rẹ* (*Oníkòyí*)

A lè pe irúfẹ́ òkè yìí ni ọfọ̀ àgbélépọ̀tá. Ẹ̀gìí, ìyàwó Oníkòyí ni Rọ́bọnmì pé ọfọ̀ yìí sí.

Ìyàwó Oníkòyí náà fèsì, ó ní:

*Arósùn lorúkọ táà pòṣùká*

*Anàgbalaja kale lóruko̩ òòrùn*

*Wọ́n ní kó ka, kò kì í ká ohùn ọ̀nà kò*

*Lorúkọ tá ń paláǹtakùn.*

*Nígbà tí àkéréjùpọ́n bá ti tagbo*

*Ọjọ́ náà ní fojú kan ìlẹ̀pa*

*Ó yá oorun lójú yin* (*Oníkòyí*)

A tún lè pe irúfẹ́ ọfọ̀ òkè yìí ní ọfọ̀ àṣẹ. Ọfọ̀ òkè yìí ni ìyàwó Oníkòyí pè sí Àrọ̀nì, Rọ́bọnmi àti àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀. Àwọn ọmọ ẹ̀yìn Àrọ̀nì àti Rọ́bọnmì sùn fún ìgbà díẹ̀ kí iyè wọn tó là padà. Àrọ̀nì náà kí ọfọ̀ bẹnu, ó ní:

*Oò mọ̀ pé a kì í sági lọ́bẹ́*

*A kì í dọ́mọ àrọ̀gìdìgbà lokùn*

*Tilé tile kann kì ì tilé ọjọ́*

*Tilẹ̀kùn tilẹ̀kùn kan kì í tilẹ̀kùn ọjà* (*Oníkòyí*)

A lè pe ọfọ̀ yìí kan náà ni ọfọ̀ arọ̀bi. Bí àwọn alagbára ti máa ń ṣe àmúlò ọfọ̀ láàrin ara wọn pàápàá jù lọ ti wọ́n bá ń fagagbága ni oníffìmù ti ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀. Bákan náà, bí ìṣàmúlò ọfọ̀ ti máa ń ṣe àfihàn agbára tó wà nínú ọ̀rọ̀ ẹnu Yorùbá ni onífíìmù ti ṣe àgbékalẹ̀ rẹ̀ nínú fíìmù àgbéléwò yìí.

Nínú fíìmù "Orí Ẹni" nígbà tì ọba ìlú Àli-Ọ̀yun kú, àwọn afọbajẹ rí i pé Ọbalọ́la ni orí oyè kàn. Wọ́n fi ọ̀rọ̀ tó Ọbalọ́la létí ṣùgbọ́n ọ̀rọ̀ náà gba òdì lára rẹ̀. Ìdí ni pé gbogbo ọba tó tí ń jẹ ní ìlú Àli-Ọ̀yun kì í pẹ́ lórí oyè tì wọ́n fi máa ń wàjà. Ọbalọ́la gba ilé Balógun lọ pẹ̀lú àdá lọ́wọ́ láti fi ẹ̀hónú hàn. Bí ó ti yọ lọ́ọ̀ọ́kán ni Balógun ki ọfọ̀ bọnu pé:

*Ní sùúrù*
*Òòṣà bí òòṣà oko*
*Wọn kì í rójú lasẹ̀ pẹ́pẹ́yẹ*
*Ju àdá ọwọ́ rẹ̀ sílẹ̀* (*Orí Ẹni*)

Ọfọ̀ òkè yìí ni Balógun pè tí Ọbalọla sì ju àdá ọwó rẹ̀ sílẹ̀. Ọbalọ́la dáhùn. Ó ní:

*Kí n fàdá sílẹ̀* (*Orí Ẹni*)

Lẹ́yìn èyí ni Balógun tún fi òté mìíràn lé e fún Ọbalọ́la. Ó sọ̀rọ̀, ó ní:

*Bí òrí bá ti ń fojú kòòrùn,*
*Inú rẹ̀ yọ́ ni.* (*Orí Ẹni*)

Bí Balógun ti pe ọfọ̀ kejì ni inú Ọbalọ́la yọ́ tí ó sì gbàgbé ìpinnu rẹ̀ láti pa Balógun. Àwọn Yorùbá a máa lo ọfọ̀ gẹ́gẹ́ bí wọ́n ti lò ó nínú fíìmù àgbéléwò yìí láti yọ ara wọn kúrò nínú ewu tàbí ikú òjijì. Bí onífíìmù ti ṣe àmùlò ọfọ̀ yìí bá ìlànà àgbékalẹ̀ ọfọ̀ Yorùbá mu. A lè pe ọfọ̀ òkè yìí ni ọfọ̀ àṣẹ.

Onírúuru ọfọ̀ ló kún inù fíìmù àgbéléwò "Ògbórí Ẹlẹ́mọ̀shọ́." Èyí kò ṣàìrí bẹ́ẹ̀ torí ìtàn fíìmù àgbéléwò yìí dá lórí ìjà àwọn alágbára. Ibi tí èyí bá ti ṣẹlẹ̀, ìṣàmúlò ọfọ̀ kì í gbẹ́yìn. Ọjọ́ tí Ṣọ̀ún dé ibùba Ìdágìrì, ó kọ́kọ́ fún ọ̀kan nínú àwọn ọmọ ẹ̀yìn rẹ̀ tó kọ́kọ́ fojú gàn-àn rẹ̀ lọ̀rùn pa. ibi tí ó ti ń ṣe èyí lọ́wọ́ ni ó ti pàṣẹ fún àwọn yòókú pẹ̀lú ọfọ̀ pé wọn kò gbọdò yẹsẹ̀. Ó ní:

*Ẹ̀yin ẹ dúró báun*
*Ẹ̀gún kánkán kì í jẹ́ kí a gbá kánkán mú*
*Ìbẹ̀rù bojo kì í jẹ́ kí á tọmọ ejo mọ́lẹ̀*
*Orí kan ṣoṣo ni ejò ni, ti fíí túgba orí ka.*
*Bàbá mi ìbà*
*Bádìẹ ṣogún, ṣọgbọ̀n*
*Àgò ní ó dé e* (*Ògbórí Ẹlẹ́mọ̀shọ́*)

Nínú ọ̀fọ̀ Ṣọ̀ún òkè yìí, gẹ́gẹ́ bí àkóònú rẹ̀, kò sí ẹnikan tó le di kánkán mú torí ẹ̀gún rẹ̀. Bẹ́ẹ̀, ẹ̀rù kì í lè jẹ́ kí ènìyàn tẹ ọmọ ejò mọ́lẹ̀. Bí ejò bá sì yọ sí igba ènìyàn, ṣe ni wọ́n máa ń túká. A lè pe ọ̀fọ̀ òkè yìí ní ọ̀fọ̀ àṣẹ tí a fi máa ń ṣe àgbékalẹ̀ òtítọ́ àyérayé. Lóòótọ́, kò sí ẹni tó lè kojú Sọ̀un tàbí dì í mu nínú àwọn ọmọ ẹ̀yìn Ìdágìrì. Nínú ọ̀fọ̀ yìí ni Sọ̀ún ti sọ ara rẹ̀ di ejò tíí tu ọ̀pọ̀ ènìyàn ká. A rí wí pé kò sí ẹni tó yẹsẹ̀ nínú àwọn ọmọ ẹ̀yìn Ìdágìrì tó fi lù wọ́n ní oògùn pa.

Irúfẹ́ ọ̀fọ̀ mìíràn tí a rí tọ́ka sí jẹ yọ nígbà tí ìjà Ẹlẹ́mọ̀ṣọ́ àti Ṣọ̀ún gbóná janjan. Àwọn méjèèjì ti pa itú méje ti alágbara méjì máa ń pa. Ṣùgbọ́n tí irin bá kan irin, ó di dandan, ọ̀kan gbọ́dọ̀ tẹ̀ fún èkejì. Èyí ló mú Ṣọ̀ún tẹnu bọ ọ̀fọ̀ ìsàlẹ̀ yìí pé:

*Mo ní párá nilé ọkọ́*
*Mo ní pàrà nilé ọkọ́*
*Mo ní párá nilé ọkọ́*
*Ọ̀dẹ̀dẹ̀ ni yàrá àdá*
*Àdá toko bọ àdá sùn gbọnrangandan*
*Ìdákúdàá nígbà ewú dá*
*Ìgbàkugbà lẹ̀tù gbà*
*Ẹlẹ́mọ̀ṣọ́ ilẹ̀ gbọnrangandan* (*Ògbórí Ẹlẹ́mọ̀ṣọ̀*)

Nínú ọ̀fọ̀ òkè yìí, Sọ̀ún ṣe àmúlò ọkọ́ àti àdá. Bí àgbẹ̀ bá mú ọkọ́ àti àdà lọ láti fi ṣe iṣẹ́ nínú oko, bí ó bá délé a fi ọkọ́ àti àdá náà pamọ́. Nńkan ti kò lẹ́mìn-ín ni ọkọ́ àti àdá. Ojú kan tí àgbẹ̀ bá fi wọn sí ni wọ̀n máa wà di ọjọ́ kejí. Ọ̀fọ̀ àṣe ni a lè pe ọ̀fọ̀ òkè yìí. Ṣọ̀ún pe ọ̀fọ̀ òkè yìí láti jẹ́ kí irúfẹ́ oorun àsùnjù tí àdá máa ń sùn sẹlẹ̀ sí Ẹlẹ́mọ̀ṣọ́. A sì rí wí pé ọ̀fọ̀ yìí náà ni Ṣọ̀ún pè gbẹ̀yìn láti fi ségun Ẹlẹ́mọ̀ṣọ́. Bí Ṣọ̀ún ti pé ọ̀fọ̀ yìí tàn ni Ẹlẹ́mọ̀ṣọ́ ṣubú lulẹ̀ tí Ṣọ̀ún sì gé orí rẹ̀. Àwọn alágbára méjì a máa ṣe àmúlò ọ̀fọ̀ láàrin ara wọn bí ọ̀rọ̀ bá ṣe bí ìjà gẹ́gẹ́ bí ó ti sẹlẹ̀ nínú fìímù àgbéléwò yìí.

## Àgbálọgbábọ̀

Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú ohun tó jẹ iṣẹ́ yìí lógún ni ìlò ọ̀fọ̀ nínú àsàyàn fìímù àgbéléwò Yorùbá. Nipa báyìí, iṣẹ́ yìí yànnàmí díẹ̀ nínú iṣẹ́ tó wà nílẹ̀ lórí fìímù àgbéléwò Yorùbá àti ọ̀fọ̀. Lẹ́yìn èyí ni a ṣe àgbéyẹ̀wò ìlo ọ̀fọ̀ bí ó se jẹyọ nínú àwọn fìímù àgbéléwò tí a yàn láàyò. A wo àgbékalẹ̀ ìlò ọ̀fọ̀ nínú fìímù àgbéléwò àwọn òṣèré mẹ́rin tí a ṣe àsàyàn iṣẹ́ wọn. Àwọn òṣèré náà ni Lérè Pàímọ́, Yínká Quadri, Táíwò Hassan àti Adébáyọ̀ Fálétí.

Àbájáde iṣẹ́ yìí fihàn pé ọ̀fọ̀ lágbára lórí oògùn. A lè sọ àsọyán pe ọ̀fọ̀ ni kọ́kọ́rọ́ tí a fi ń sílẹ̀kùn oògun. Iṣẹ́ yìí jẹ́ kí á mọ̀ pé ọ̀rọ̀ ẹnu tí a mọ̀ sí ọ̀fọ̀ lágbára gan-an, ó sì jẹ́ ọ̀kan nínú orísun agbára Yorùbá.

# ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ

Adágbádá, O. (2005). Woman folk in Yorùbá Film Industry PhD Thesese Department of Linguistics and African Languages, University of Ìbàdàn.

Adélékè, D. A (1995). Audience Rrecption of Yorùbá Fíìmù: Ìbàdán as a case study. Ph. D Thesis, Ìbàdàn, University of Ìbàdàn.

Fábùnmi, A. (1972) Àyàjọ́: Ìjìnlẹ̀ Ohùn Ifẹ̀. Ìbàdàn: Oníbọ̀njé Press.

Ọdéjọbí, C. O. (1991). Ìlò Ohùn Àbáláyé Nínú Fíìmù Àgbéléwò Yorùbá "Ègún Àìmọ̀" láti ọwọ́ Sọlá Mike Agboọlá.

Ọlábimtán, A. (1980). Ọgbọ́n Ìtọpinpin Ewì Yorùbá. Macmillan, Lagos.

Ọlátúnjí, O. (1984). Feature of Yorùbá oral poetry. Ìbàdàn University Press Ltd.

Ológundúdú, D. (2008). The oracle of Yorùbá culture. United Kingdom Institute of Yorùbá culture.

Ọ̀pẹ̀fẹ̀yítìmí, J. (2011). Àṣẹ Inú Ewì, Àwísẹ Nínú Ẹ̀gin Jọ́nà Iṣé Akadá Ní Èdè Yorùbá P.13-23

Ọ̀pẹ̀fẹ̀yítìmí, J. A. (1984). "Ìwúre Yorùbá Supplicatory Blessing Chants" M. A. Thesis, Ilé-Ifẹ̀, University of Ifẹ̀.

Rájí, S. M. (1991). Ìjìnlẹ̀ Ọfọ̀, Ògèdè àti Àásán. Ìbàdàn: Oníbọ̀njé Press.

**Àwọn Fíìmù Àgbáléwò tí a lò**

Adébáyọ̀ Fálétí (2009) *Orí Ẹni, Apafan Productions, Lagos.*

*Adébáyọ̀ Fálétí* (2010) *Basọ̀run Gáà, Apafan Productions, Lagos.*

*Adébáyọ̀ Fálétí* (2010) *Oníkòyí, Apafan Productions, Lagos.*

*Lérè Pàímọ́* (2009). *Ògbórí Ẹlẹ́mọ̀ṣọ́, Afẹ́lẹ̀lẹ & Brothers* (*Nig.*) *Ltd, Lagos.*

*Lérè Pàímọ́* (2012). *Ògún Lákáayé, Ẹ̀dá Film Productions, Lagos.*

*Táíwò Hassan* (2012). *Ẹní Jogùn, Ògògó Films Productions, Lagos.*

*Táíwò Hassan* (2012). *Ọ̀pá Àṣẹ, Ògògó Films Productions, Lagos.*

*Yínká Quadri* (2011). *Ọ̀nà Lójìn, Yinka Quadri Productions, Lagos.*